# Àgbéyẹ̀wò Ìlò Ọnà Èdè Nínú Ètò Kókó-Inú-Ìwé Ìròyìn Ti Rédíò Ìfẹ́sowápò (Bond FM) 92.9

*Oluwatobiloba Lawal & Okegbemi, Taiwo Wahab*


## Àṣamò

*Ni awùjọ̀ sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀ Yorùbá, ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti sọ̀rọ̀ nípa ohun tí à ń pè ní ọnà èdè àti ìṣàmúlò àwọn ọnà èdè bẹ́ẹ̀ nínú orin, ewì, ìtàn àròsọ, eré oníṣe, ìpolówó ọjà abbl. Sùgbọ́n, akitiyan kò ti kúnjú òsùwòn lórí ìlò ọnà èdè nínú àwọn oríṣiríṣi ètò lórí rédíò pàápàá jùlọ ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Àfojúsùn iṣẹ́ yìí ni láti tọpinpin ìlò ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn pẹ̀lú èrò láti wo bóyá ìlò wọn tọ̀nà, iṣẹ́ tí a ń fi wọ́n jẹ́ àti àyọrísí rẹ̀. A ṣe àgbálẹ̀ ètò náà fún ọ̀sẹ̀ méjìlá láti ri ògòòrò détà fún ìtúpalẹ̀. Síwájú si, a ṣe ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ọ̀kan lára àwọn atọ́kùn ètò náà láti ni ìmò ìpìlẹ̀ àti òye kíkún nípa ètò náà àti ìlò èdè nínú rẹ̀. Pépà yìí ri dájú pé ọnà èdè jẹ́ àbùdá pàtàkì fún ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, wọ́n máa ń ṣe àmúlò rẹ̀ dúnjú tó fi jẹ́ pé a kò le gbé kókó ìròyìn mẹ́ta jáde kí a máa rí ọnà èdè nínú méjì nínú rẹ̀. Ìwádìí àti àtúpalẹ̀ ọnà èdè nínú kókó-inú-ìwé-ìròyìn sàfihàn pé ìlò ọnà èdè tọ̀nà nínú ètò yìí. Lára àwọn iṣẹ́ tí ọnà èdè ń ṣe nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn ní àfihàn àti àlàyé kókó ìròyìn, àpèjúwe àti àpẹẹre àwọn kókó ìròyìn abbl. O tún máa ń wùlò fún pípẹ́ ọ̀rọ̀ sọ láti dẹ́kun wàhálà tí sísọ ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ sákálá yóò dá sílẹ̀ láwùjọ. Pépà yìí fẹnukọ̀ pé ọnà èdè wúlò púpọ̀ fún ètò ṣíṣe lórí rédíò pàáàá jùlọ nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Bákan náà, a ri dájú pé àlòjù ọnà èdè nínú ètò náà máa ń fa àwọn àléébù kan nítorí náà ìmòràn wa ni pé kí a yàgò fún àlòjù rẹ̀*


*Kókó-ọ̀rọ̀:* *ọnà èdè, rédíò, ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, Bond FM 92.9.*

## Ìfáárà

Rédíò jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àti ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ ní àwùjọ ọmọnìyàn. Ẹ̀rọ yìí máa ń kó ipa pàtàkì ní àwùjọ nípa ṣíṣe ìtànkálẹ̀ ìròyìn, kíkọ́ ni lẹ́kọ̀ọ́, líla àwọn ènìyàn lóyẹ nípa ǹnkan tó ń lọ lọ́wọ́ ni àwùjọ. Bákan náà, á ma kìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́; bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà burúkú láwùjọ, á máa kín àwọn ọlọ́gbọ́n lẹ́yìn, á sì máa gbóríyìn fún àwọn tí ó ń hùwà tó tọ́ láwùjọ, èyí tó máa ń mú ìtẹ̀síwájú débá ìlú, á sì tún máa dín ìwà ìbàjẹ́ kù láwùjọ. Láti jẹ́ àwọn iṣẹ́ pàtàkì tí rẹ́díò ń ṣe yìí, wọ́n máa ń ṣe àgbékalè ètò lóríṣiríṣi láti ṣe kòkárí àwọn iṣẹ́ yìí. Ètò yìí ni àwọn atọ̀kùn ilé iṣẹ́ ìgbóhùn sáfẹ́fẹ́ maá ń gbà gbé ìròyìn, ọ̀rọ̀ tó ń lọ tàbí àwọn kókó àwùjọ míìràn jáde lọ́nà òkan-ò-jọ̀kan lójoojúmọ́ tàbí lọ́sọ̀ọ̀sẹ̀ ní àkókò kan sí àkókò míìràn.

Èdè ní ọkọ̀ tí rédíò máa ń lo fún iṣẹ́ ìbánisòrò tí ó ń jẹ́ ní àwùjọ. Gbogbo ǹnkan tí a ń sọ, tí àwọn ènìyàn ń gbọ́ lórí rẹ̀díò, èdè ni a máa fi ń gbe jáde. Láì sí

èdè, ìbánisọ̀rọ̀, ètò ṣíṣe àti ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ kò sé é se lórí rédíò. Ọ̀nà èdè ni àwọn èròjà amédèdùn tí aṣafọ̀ ń lò láti mú adùn èdè wọ inú afọ̀ rẹ̀. Ọ̀nà èdè jẹ́ ohun kan gbòógì tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú ètò ṣíṣe lórí rédíò, ó máa ń fún kókó tí asọ̀ròyìn ń kà ní ẹwà tí yóò jẹ́ kí ètò náà dùn gbọ́ fún àwọn olùgbọ́ tí wọ́n yóò má fi ọkàn bá ètò náà lọ.

Oríṣirísi àrà ni àwọn atọ́kùn ètò àti akàròyìn máa ń dá pẹ̀lú èdè àti ọnà èdè lórí rédíò. Àwọn kan máa ń lò wọn dáadáa àti bí ó ti tọ́. Èwè, àwọn kan máa ń lò wọ́n láì bìkítà fún ìpò ìlò wọn àti ìtumọ̀ tí wọ́n mú dání. Pépà yìí fẹ́ ṣe àyẹ̀wò bí àwọn atọ́kùn ètò ṣe ń lo ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé ìròyìn; bóyá ó tọ̀nà tàbí kò tọ̀nà, àti iṣẹ́ tí wọ́n ń fi àwọn èròjà amédèdùn yìí jẹ́ nínú ètò náà. Ìdí tí a fi yán ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn bí àwòtà nínú iṣẹ́ yìí ni pé ó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ètò díẹ̀ lórí rédíò tí wọ́n tí máa ń lo èdè Yorùbá dúnjú láìsí àmúlùmálà pẹ̀lú èdè mìíràn lójoojúmọ́. Nínú pépà yìí, a ó ṣe àfihàn àwọn ọnà èdè tí ó wón ń lò nínú ètò náà àti bi wọ́n ṣe ń lò wọ́n, pàtàkì èdè náà nínú ètò àti àléébù tí ìlò rẹ̀ ń mú bá ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn.

## Ọnà Èdè

Ọnà èdè ní àwọn horo ọ̀rọ̀, àpólà tàbí gbólóhùn nínú èdè tí aṣafọ̀ máa ń lò láti fún ọ̀rọ̀ rẹ̀ ní adùn àti iyì òye kíkún nípa èdè. Ọnà èdè dàbí irú nínú ọbẹ̀; ó máa ń bu ẹwà àti adùn kún ọ̀rọ̀ bí irú ṣe máa ń mú ọbẹ̀ dùn. Ọnà èdè ní kì í jẹ́ kí ìsọ dàbí ọ̀rọ̀ sákálá nítorí àrà ọ̀tọ̀ ní ìsọ bẹ́ẹ̀ yóò bá jáde n ípasẹ̀ ọnà èdè tí a bá lò pẹ̀lú ìsọ náà. Bí ènìyàn bá ṣe gbọ́ èdè dúnjú tó ní agbára ènìyàn láti lo ọnà èdè yóò ṣe kún tó. Kẹ́hìndé (2001) sàlàyé pé àwọn ọnà èdè Yorùbá ni a le pè ní àkànlò-èdè ayàwòrán. Èyí ni ìlò èdè amúṣẹ́-ọ̀nà-lítíréṣọ̀-rẹwà tí oníṣẹ́ ọnà máa ń ṣe àmúlò rẹ̀ nínú iṣẹ́ wọn. Oníṣẹ́ ọnà lítírésò á máa lo àwọn akànlò èdè ayàwòrán wọ̀nyí pẹ̀lú èròngbà láti fi ẹwà kún èdè tí wọ́n ń gbé jade àti láti fún àwọn olùgbọ wọn ní ìtumọ̀ kíkún sí ohun tí wọ́n fẹ́ sọ. Ọnà èdè máa ń fi ọgbọ́n, ìmọ̀, àti òye tí ó báwà nínú irúfẹ́ iṣẹ́ ọ̀nà náà hàn. Ọ̀nà èdè máa ń wakọ̀ kókó kan pàtó gúnlẹ̀ nínú àgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọ̀nà lọnà tí yóò mú kí àwàgúnlẹ̀ tirẹ̀ yé àwọn olùgbọ tàbí òǹkàwé dáadáa.

Síwájú si, Àkànmú àti Sanni (2011) pe àwọn ọnà èdè Yorùbá ní àwọn eròjà amédèdùn. Wọ́n ṣàlàyé pé àwọn èdè yìí ni ó máa ń fún kókó tí akéwi tàbí òǹkọ̀wé ń kọ ní ẹwà tí ó sì mú kí iṣẹ́ wọn dùn kà. Wọ́n ṣàfihàn àwọn ọnà èdè Yorùbá bi: Àfiwé, Àfidípò, Ìfohunpèèyàn, Gbólóhùn adọ́gba, Fìrósínròòjẹ, Fìrómọ̀rísí, Ìfọ̀rọ̀dárà, Àwítúnwí, Àkànlò èdè àti Òwe. Ọnà èdè pọ̀ jántìrẹrẹ nínú èdè Yorùbá yàtọ̀ sí èyí tí àwọn onímọ̀ tí tọ́ka. Lára wọn ni ọ̀rọ̀ ìkàsì, àsọrégèé, ìṣẹ́wẹ́kú, àpẹ́sọ, àdàpè, ìtakora ọ̀rọ̀, ajọrọ̀sòótọ́, ìbéèrè pèsìjẹ, ìlò èdè àjòjì, ọ̀rọ̀ àyálò, ẹ̀ka-èdè, àmúlùmálà kóòdù, ìpààrọ̀ koodu, àmúlùmálà èdè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àfojúsùn wa nínú ìwádìí yìí ni àwọn èyí tí wọ́n ṣe pàtàkì ní àwùjọ sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀ pàápàá lórí rédíò. Àwọn ọnà èdè tí wọ́n gbajúmọ̀ ni àárín àwọn oníròyìn àti àwon tí atọ́kùn ètò

lórísirísi máa ń lò tí a máa ń bá pàdé lórí rédíò ni òwe, àkànlò èdè, àwítúnwi, ìbéèrè pèsìjẹ, ìṣẹwẹ́kú, ìsohundènìyàn, ìfọ̀rọ̀dárà, èdè ajòjì, àmúlùmálà kóòdù àti orin. Òwe ni àkójọpọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ń fi ìjìnlẹ̀ ọgbọ́n àti òye àwọn àgbà hàn nípa ohunkóhun tí wọ́n ti rí ìrírí nípa rẹ̀. Àkànlò èdè jẹmọ́ gígan ọ̀rọ̀ sọ nípa lílo èdè kíkún tí ó nílò òye láti túmọ̀ wọn. Àwítúnwí ni gbígbé àmì kan jáde ju ẹ̀kan lọ. Ó lè jẹ́ àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀, òye ọ̀rọ̀, alákùdé gbólóhùn àti odindin gbólóhùn. Ìbéère pèsìjẹ ni ọnà èdè tí a fí ń bèrè ọ̀rọ̀ tí kò nílò ìdáhùn. Ìsewẹ́kú níṣe pẹ̀lú lílo ọ̀rọ̀ lọ́nà tó tọ́ nínú ìsọ. Ìsohundènìyàn jẹmọ́ fífún ǹnkan tí kì í ṣe ènìyàn ní àbùdá àdání fún ènìyàn. Ìfọ̀rọ̀dárà níṣe pẹ̀lú ṣíṣe àpètúnpè ọ̀rọ̀ kan lọ́nà àrà tí yóò mú ẹwà èdè jáde. Èdè ajòjì ni ìṣàmúlò àwọn èdè mìíràn tó yàtọ̀ sí èdè Yorùbá nínú ìsọ láti fi gbé kókó kan jáde. Àmúlùmálà kóòdù ni ìlò èdè méjì mọ́ra wọn nínú ìsọ kan; kí a bẹ̀rẹ̀ ìsọ kan pẹ̀lú èdè Yorùbá, kí a fi èdè mìíràn bí Gèésì si láàrín kí a tó wá fi èdè Yorùbá parí ìsọ náà. Orin ni ìlò àwọn wákà àti orin aládùn lóríṣiríṣi láti fi kín ọ̀rọ̀ lẹ́yìn tàbí láti sàfihàn kókó ọ̀rọ̀.

Gbogbo àwọn ọnà èdè yìí ni wọ́n maa ń hànde nínú àwọn ètò oríṣiríṣi tí wọ́n máa ń ṣe lórí rédíò tí ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn kò gbẹ́yìn nínú wọn. Àwọn ọnà èdè wọ̀nyí ni wọ́n ń jẹ́ ki ètò dùn gbọ́ tí àwọn olùgbọ́ yóò sì máa fọkàn bá wọn lọ. A máa ń rí alòpọ̀ oríṣríṣi àwọn èròjà amédèdùn yìí láti ìbẹ̀rẹ̀ ètò títí dé ìparí rẹ̀.

## Ètò Kókó-Inú-Ìwé Ìròyìn

Ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn bẹ̀rẹ̀ nínú oṣù kẹjọ, odùn 1999. Ẹni tí ó ṣe àgbékalè ètò yìí ni ọmọ Ọba Atiládé Atóyèbí tí ó jẹ́ alákóso Radio Nigeria nígbà náà. Olùdásílẹ̀ ètò yìí wòye pé àwọn ènìyàn tí ń gbọ́ ohun tí ó ń lọ ní àwùjọ tí ó sì ń jẹyo nínú àwọn ìwé ìròyìn ní èdè Gẹ̀ẹ́sì lórí rédíò ṣùgbọ́n kò tì í sí irú akitiyan yìí ní èdè Yorùbá pàápàá jùlọ ní ìlú Èkó tí ilé-ìṣẹ́ náà wà. Síwájú si, wọ́n tún ròó pè bí ó bá tilẹ̀ wà ní Èkó, kò tí ì kárí. Bàbá yìí ni ó wá dábàá pé kí wọ́n bẹ̀rẹ̀ ohun tí wọ́n ń pè ní "àjọyọ̀" èyí ni pé yíyọ àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí ó máa ń jẹyọ nínú àwọn ìwé ìròyìn ojoojúmọ́ ilẹ̀ wa kí a sì máa kà á fún ènìyàn lórí rédíò pẹ̀lú èdè Yorùbá. Ara akitiyan, ìṣe àti iṣẹ́ tí ètò náà ń jẹ́ ni a ti yọ orúkọ rẹ̀, kókó inú ìwé ìròyìn. Ẹni àkọ́kọ́ tí ó kọ́kọ́ ṣe ètò kókó inú ìwé ìròyìn ni Ọgbẹ́ni Ṣẹ́gun Ọrẹ́bẹ̀lá tí ó jẹ́ olórí Ẹ̀ka èdè Yorùbá ní ilé-iṣẹ́ Bond FM nígbà náà. Lẹ́yìn rẹ̀ ni Alàgbà Bùkọ́lá Oshinsanwo. Àwọn enìyàn púpọ̀ ni wọ́n ti ṣe ètò náà títí di òní, lara won ni; Táíwò Akínṣolá, Tajudeen Àjàní Ojúẹlẹ́gba, Ọláńrewájú Awóreni, Túnjí Ọlálékan, Adédèjì Morufudeen Olúyege, Bísọ́lá Balógun, Ọrẹolúwa Ogùnnaike, Faaoziyah Sanni, Abdulfatai Abdulgafar, Monsuru Karonwi, Olóògbé Kẹ́hìndé Jimoh, Tèmítọ́pe Oyèfolú, Ganiyat Aṣiru, Adétóún Olúwọlé (ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Túnjí Ọlálékan).

Ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn máa ń wáyé lórí Bond FM 92.9 ní ìpínlẹ̀ Èkó ní aago mẹ́fà kọjá ìṣẹ́jú mẹ́ẹ̀dògún sí aago mẹ́sàn-án kọjá ìṣẹ́jú mẹ́ẹ̀dógún lójoojúmọ. Àwọn ètò kékèké mẹ́ta wà nínú kókó inú ìwé ìròyìn tí a máa ń ṣe lábẹ́ rẹ̀ àti nínú àsìkò ètò náà ìdí nìyí tí ètò náà fi máa ń wáyé fún wákàtí mẹ́ta. Àwọn ètò

métèétà inú rẹ̀ ni; bọ́nà-ṣe-rí, gbàgede-ọ̀rọ̀ àti lórí-pápá. Ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn pọ́ńbélé (tí a ti máa ń ṣe àjọyọ) apá kínní máa wáyé láàrín aago mẹ́fà kọjá ìṣẹ́jú mẹ́ẹ̀dògụ́n sí aago méje. Aago méje si aago méje kọjá ìsẹjú mẹ́ẹ̀dógún ni àwọn atọ́kùn máa ń ka àtẹ̀ránṣẹ àwọn olùgbọ́ lórí ọ̀rọ̀ tí wọ́n fẹ́ kí àwọn ènìyàn bá wọn dásí tí wọ́n yán létí wọn bí wọ́n ṣe bẹ̀rẹ̀ ètò. Abala bọ́nà-ṣe-rí tí àwọn ènìyàn tí máa ń pè wọlé láti sọ ǹnkan tó ń lọ lójú ọ̀nà ládùgbò wọn ní yóò tẹ̀le láti aago méje kọjá ìsẹjú mẹ́ẹ̀dógún sí aago mẹ́jọ ku ìsẹjú mẹ́ẹ̀dógún. Ètò gbàgede-ọ̀rọ̀ tí àwọn ènìyàn tí ń sọ ǹnkan tó ń lọ ládùgbò wọn tí wọ́n fẹ́ kí ìjọba bá wọn dásí ni wọ́n máa ṣe títí di aago mẹ́jo. Kókó-inú-ìwé-ìròyìn pọ́ńbélé apá kejì yóò wáyé láàrín aago mẹ́jọ sí aago mẹ́jọ-àbọ̀. Ìkéde lóríṣiríṣi àti ìpolówó ọjà yóò wáyé fún ìsẹjú mẹ́ẹ̀dógún títí di aago mẹ́sàn-án ku ìsẹjú mẹ́ẹ̀dógún. Abala lórí pápá tí wọ́n ti ń mú ìròyìn eré ìdáraya lóríṣiríṣi wá ni wọn yóò ṣe titi di aago mẹ́sàn-án kọjá ìsẹjú mẹ́ẹ̀dógún. Ètò lórí pápá yìí ni wọ́n máa fi kádìí ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Gbogbo àwọn abala yìí ni wọ́n ní atọ́kùn ètò ti wọn tó yàtọ̀ sí àwọn tí wọ́n ń ṣe kókó-inú-ìwé-ìròyìn pọ́nbélé.

Kókó-inú-ìwé-ìròyìn pọ́nbélé tí ó jẹ wá lógún nínú pépà yìí máa ń wáyé fún wákàtí kan àti ìṣẹjú mẹ́ẹ̀dógún nínú wákàtí méta tí a fi ń ṣe ètò náà. Apá kín-ín-ní máa ń wáyé láàrín aago mẹ́fà kọjá ìṣẹ́jú mẹ́ẹ̀dògụ́n sí aago méje fún ìsẹjú márùndínláàádọ́ta. Apá kejì máa ń wáyé láàrín aago mẹ́jọ sí aago mẹ́jọ-àbọ̀ fún ọgbọ̀n ìsẹjú. Àwọn atọ́kùn ètò a máa fa kókó yọ nínú oriṣiriṣi ìwé ìròyìn tí ó jáde lọ́jọ́ náà. Àwọn ìwé ìròyìn tí wọ́n máa ń ṣàmúlò ni Nigerian Tribune,The Guardian, The Punch, Vanguard, The Nation, Daily Sun, Independent, New telegragh, Daily Express, Daily Telegragh, Daily Mirror, Daily Star, News Now, Complete sport, Olympic Sports.

Ètò máa ń bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú orin ìṣíde tí o máa ń ta àwọn ènìyàn lólobó pè ètò náà ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀ tí wọn yóò fi fẹtí lélẹ̀ láti gbọ́ àwọn kókó tí ó wà nínú ìwé ìròyìn láàárò ọjọ́ náà. Orin ìṣíde ètò náà máa ń lọ báyìí;

Kókó inú ìwé ìròyìn,
Ìfẹ́sowápọ̀ tún gbe dé o,
Kókó inú ìwé ìròyìn,
Ẹ wá nǹkan fìdí lé ẹ jẹ́ a jọ gbọ,
Kókó inú ìwé ìròyiǹ,
Ìfẹ́sowápọ̀ tún gbe dé o,
Ní bi atọ́kùn ń pèdè bí ẹnilááyin,
Kókó inú ìwé ìròyìn,
Ẹ gbọ́rọ̀ lẹ́nu onílàákàyè,
Àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ tó jojú gbèṣè,
Kókó inú ìwẹ́ ìròyìn,
Àtúpalẹ̀ èdè òyìnbò sí ti wa,

Kókó inú ìwé ìròyìn......
Bond FM.... 92.9.

Lẹ́yìn orin ìṣíde yìí ni àwọn atọ́kùn yóò sàfihàn ara wọn nípa dídárúkọ wọn fún àwọn olùgbọ́ lọ́nà àrà pẹ̀lú oríṣiríṣi ìnagije àti ọnà èdè. Àwọn atọ́kùn yóò wa bẹ̀rẹ̀ sí ni mú àwọn kókó tó súyọ nínú àwọn ìwé ìròyìn lọ́jọ́ náà jáde fún àwọn ènìyàn. Bí àpẹẹrẹ,

> Ní ojú iwé kẹta ìwé ìròyìn Daily Times, "Ìbànújẹ́ górí ẹ̀mí Tinubu lórí èrò rẹ̀ láti jẹ Ààrẹ orílé-èdè Nàìjíríà" Èmi kọ́ ni mo sọ́ o, ọ̀kan nínú àwọn agbẹnusọ rẹ̀ ló sọ ọ́ di mímọ̀ fún àwọn oníròyìn.
>
> Ní ojú iwé kejì ìwé ìròyìn Vanguard "Àwọn Mùsùlùmí tó ṣekú pa Dèbórà nítorí ọ̀rọ̀ èsìn kò ní wọ párádísè".

Wọ́n á ṣàlàyé àwọn kókó wọ̀nyí ní ìwọ̀nba láti fún àwọn ènìyàn lóye ìròyìn náà. Wọ́n a wá ní kí àwọn olùgbọ́ lọ sínú ìwé ìròyìn láti ka ìròyìn náà. Bí àpẹẹrẹ:

> Nínú ìwé ìròyìn The Guardian, "ọlọ́pàá ní kí ń bọ́ra sílẹ̀ láti mọ̀ bóyá obìnrin ni mí torí mo ní irùngbọ̀n". "Ẹ lọ sínú ìwè ìròyìn The Guardian lááṛọ̀ tòní, ẹ̀ ẹ́ bá ìròyìn níbẹ̀."

Gbogbo àwọn kókó tí ó jẹyo nínú àwọn ìwé ìròyìn ni wọ́n máa mẹ́nu bà lọ́kanòjọkan. Àwọn atọ́kùn yóò máa gba ọ̀rọ̀ lẹ́nu ara wọn. Tí atọ́kùn kan bá ka kókó kan, atọ́kùn kejì yóò ka òmíìràn, bí wọn yóò ṣe máa ṣe rèé títí tí ètò yóò fi parí.

## Àgbéyẹ̀wò Ìlò Ọnà Èdè nínú Ètò Kókó-Inú-Ìwé Ìròyìn

Ọnà èdè jẹ́ fọ́nran pàtàkì nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Ohun pàápàá ni wọ́n máa fí ń gbé àwọn kókó tí wọ́n yọ nínú àwọn ìwé ìròyìn tí wọ́n máa ń lò fún àjọyọ lórí ètò náà jáde fún àwọn olùgbọ́ wọn. Àwọn ọnà èdè yìí máa jíṣẹ́ tí wọ́n bá ran wọn tàbí tí a fẹ́ fi ṣe ní ọ̀gángán ipò ìlò wọn bí wọ́n ṣe ń bu èwà kún àjọyọ tí wọ́n ń ṣe. Oríṣiríṣi àwọn èròjà amédèdùn yìí ni wọ́n máa ń lò lórí ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Àwọn tí a sàkíyèsí gẹ́gẹ́ bí kòsémáàlò nínú ètò náà bí a ṣe ri nínú àgbáálè ètò náà fún osù mẹ́ta ni òwe, àkànlò èdè, ìbéèrè pèsìjẹ, àwítúnwi, ìṣẹwẹ́kú, ìsohundènìyàn, ìfọ̀rọ̀dárà, èdè ajòjì, àmúlùmálà kóòdù àti orin.

### (a) Òwe

Òwe gẹ́gẹ́ bí àkọ́jọpọ̀ ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ àwọn Yorùbá máa ń ṣe atọ́na fún ọ̀rọ̀ tí wọ́n bá ń ṣe atótónu lé lórí nígbà tí a bá lò wọ́n. Nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, òwe ṣe pàtàkì gan fún iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe, ohun lọ́ máa ń sàmúlò jùlọ. Wọn kò lè ka kókó mẹ́ta kí a má rí ìlò èdè nínú méjì nínú rẹ̀. Iṣe tí wọ́n fí ń Òwe jẹ́ nínú ètò yìí ni

títa àwọn olùgbọ́ ní olobó nǹkan tí yóò jẹyọ nínú kókó tí wọ́n fẹ́ fà jáde nínú ìwé ìròyìn lásìkò yẹn. Bí àpẹẹrẹ:

- *A kìí rí ẹfọ̀n ta lẹ́ẹ̀mejì,* Ẹni tó ti fìgbà kan rí jẹ́ sẹ́nétọ̀ ní ìwọ̀ òòrùn ìpínlẹ̀ kogi, ìyẹn DINO MELAYE, gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe ń sọ ọ wí pé wọn di ìbò abẹ́lé ẹni tí yoó díje dupò sẹ́nétọ̀ ni ẹgbẹ́ oṣèlú PDP, ọ̀mì ni Dino àti akẹgbẹ́ rẹ ẹ̀ Yusufu kọ́kọ́ jọ ta, kí wọ́n tó wá tún ibò abẹ́lé náà dì, kí Yusufu tó wá fi ìdí Dino Melaye rẹmi.
- Yorùbá lọ́ sọ wí pé *Àṣesílẹ̀ ni àbọ̀ wá bá,* gbógbó ọmọ ẹgbẹ́ òṣèlú APC ní ìpínlẹ̀ èkó ni wọ́n bá Tinubu yọ lórí èrò rẹ̀ láti jẹ ààrẹ orilé èdè nàíjíríà, nítorí pé òun náà ti gbìyànjú lórí ẹgbẹ́ òṣèlú APC fún ọjọ́ pípẹ́.

*A kìí rí ẹfọ̀n ta lẹ́ẹ̀mejì* jẹ́ ìpìlẹ̀ fún àlàyé kókó ìwé ìròyìn pé Dino Mèláyè fìdírẹmi nígbà tí wọ́n ṣe àtúnṣe ìdìbò abẹ́lé fún sẹ́nétọ̀ tí yóò sojú ẹgbẹ́ òsèlú PDP ní ìwọ̀ òòrùn ìpínlẹ̀ Kogi lẹ́yìn tí òun àti akẹgbẹ́ rẹ̀ Yusufu ti ta ọ̀mì nínú ìdìbò àkọ́kọ́. Àṣesílẹ̀ ni àbọ̀ wá bá jẹ́ atọ́nà fún ìròyìn pé àwọn ọmọ ẹgbẹ́ òsèlú APC ni Èkó faramọ́ èrò Tinubu láti dupò ààrẹ nítorí gbogbo akitiyan rẹ̀ lórí ẹgbẹ́ náà láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ títí di òní. A rí dájú nínú ìtúpalẹ̀ àpẹẹrẹ pé òwe ní ó ṣe atọ́nà kókó ìròyìn tí wọ́n fẹ́ gbé jádé. Láti ara òwe náà, àwọn olùgbọ́ ti mọ irú nǹkan tí wọ́n fẹ́ gbọ́.

### (b) Àkànlò èdè

Adéwọyin (2010) ṣàlàyé pe àkànlò èdè jẹ́ ọnà tí a máa ń gbà gán ọ̀rọ̀ sọ láti ya àwòran òye nǹkan tí ìsọ ní sí àwọn ènìyàn tí wọ́n ní ìmọ̀ èdè náà lọ́kàn. Nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, àwọn atọ́kùn ètò máa ń lo àkànlò èdè láti ṣàpèjúwe ìṣẹ̀lẹ̀ àti láti ya àwòran rẹ̀ sí àwọn olùgbọ́ lọ́kàn kí ìròyìn náà lè yé wọn yékéyéké. Bí àpẹẹrẹ

- Ọjọ̀gbọ́n Yẹmí Òṣíbàjọ̀ ti *f*árígá o, ó ní kò sí ohun tí ènìyàn lè ba òun sọ, ti yoó jẹ́ kí òun má díje dupò ààrẹ mọ́
- Àwọn ará ìlú ọ̀yọ́ *bu ẹnu àtẹ́ lu* ìjọba àpapọ̀ lórí bí wọn kò ṣe bìkítà lórí ètò àbò àwọn ará ìlú rárá.

*F*árígá túmọ̀ sí kí ènìyàn kọ̀ láti yí ìpinnu rẹ̀ padà lórí ọ̀rọ̀ kan. Atọ́kùn ètò lo ọnà èdè yìí láti ṣàpèjúwe ìwà igbákejì ààrẹ orílé èdè Nàìjíríà Ọjọ̀gbọ́n Yémi Oṣinbajo tó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn òǹdíje dupò ààrẹ nínú ìbò abẹ́lé ẹgbẹ́ òṣèlú APC. Èdè yìí ṣàlàyé pé kò sí nǹkan tí àwọn ènìyàn kò bá sọ nípa ọ̀rọ̀ ìdìbò náà, Ọ̀jgbọ́n Oṣinbajo yóò díje nínú ìdìbò náà. *Bu ẹnu àtẹ́ lu* túmọ̀ sí kí ènìyàn sọ̀rọ̀ búburú nípa ohun kan. Atọ́kùn ló ọnà èdè yìí láti fi ìhónú àwọn ará Ọ̀yọ́ hàn lórí ìhà tí

àwọn ìjọba kọ́ sí ọ̀rọ̀ ètò àbo ní orílé èdè Nàíjíríà pàápàá ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ tí àwọn fúlàni àti ajínigbé ń dà wọ́n láàmú.

### (d) Ìbéèrè pèsìjẹ

Ìbéèrè pèsìjẹ jẹ́ ọnà èdè tí elédè tàbí onísẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ máa ń lò láti bèrè ọ̀rọ̀ láti pe àkíyèsí àwọn ènìyàn sí ọ̀rọ̀ náà. Ìbéèrè lásán ni ìbéèrè yìí máa ń jẹ́, kò nílò ìdáhùn. Ìdáhùn sí ìbéèrè náà ni òye tí ó ma máa rókì lọ́kàn àwọn osùnsùn afọ̀. A máa ń ṣe àmúlò ìbéèrè pèsìjẹ nínú ètò kókó-inú-ìwe-ìròyìn láti jẹ́ ki àwọn òlúgbọ́ rónú jinlẹ̀ lórí kókó tí a gbé jáde nígbà tí a lò ó. A máa pe àkíyèsí wọn sí ọ̀rọ̀ náà láti jẹ́ ki ọ̀rọ̀ náà mú wọn lọ́kàn, kí wọ́n rí fi òye nínú ọ̀rọ̀ náà. Àpẹẹrẹ tí a rí nínú ètò náà ni wọ̀nyí:

- Àwọn ọmọ nàìjà tó wà lókè òkun tí ké gbàjarè sí ìjọba Buhari lórí wàháálà tí wọ́n ń kojú lórí iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe lọ́ọ̀hun àbi Èwo ni ká ṣòwòṣòwò, ká máa ko *èrè délé?* Wọ́n ní kí ìjọba pèsè iṣẹ́ tó dára fún àwọn ní orílé èdè bàbá wọn.
- Ètò ìdìbò ààrẹ orílé èdè nàíjíríà, *Kín ni ìdí tí ó fi jẹ́ pé òun lókàn*?

Ìlò àwọn ìbéèrè "Èwo ni ká ṣòwòṣòwò, ká máa ko *èrè délé?*" , "*Kín ni ìdí tí ó fi jẹ́ pé òun lókàn*?" pe àkíyèsí àwọn ènìyàn sí orí ọ̀rọ̀ tí wọ́n mẹ́nuba nínu kókó ìròyìn méjéèjì tí a ṣ'èpẹẹrẹ. Èwo ni ká ṣòwòṣòwò, ká máa ko *èrè délé* fi ìsọ̀rọ̀ àwọn ọmọ Nàìjíríà lókè òkun tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ bi akúra sùgbọ́n wọn ko ri èrè kó délé nítorí gbogbo owó tí wọ́n ń san fún ìjọba ilè-Ọba. *Kín ni ìdí tí ó fi jẹ́ pé òun lókàn* pe àkíyèsí àwọn ènìyàn sí ọ̀rọ̀ Tinubu tí ó fẹ́ dúpò ààre ilẹ̀ Nàìjíríà tí ó ní òun ni ọ́kàn láti jẹ Ààre Nàìjíríà. Ìbéèrè náà yóò jẹ́ kí àwọn ènìyàn ronú ọ̀rọ̀ rẹ̀ àti láti fẹ́ mọ ìdí tí ó fi jẹ́ òun lọ́kàn.

### (e) Ìsọhundènìyàn

Ìsọhundènìyàn jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọnà èdè tí a máa ń bá pàdé nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Àwọn atọ́kùn nígbà tí wọ́n bá ń gbé kókó ìròyìn jáde máa ń fún àwọn ohun tàbí nǹkan tí kì í ṣe ènìyàn ní àbùdá tó jẹ́ adání fún ènìyàn nìkan. Wọ́n máa ń ṣe akitiyan yìí láti ṣe àpẹẹrẹ kí òye ìròyìn náà lè hàn sí àwọn ènìyàn. A rí àpẹẹrẹ ìsọhundènìyàn yii:

- Àjọ ASUU sọ nínú àtẹjáde wọ́n lórí ẹ̀rọ aláfọ́nká túwítà (Twitter handle) pé ìròyìn tó sọ wí pé àwọn tí fagi lé ìyanṣẹ́lódì pé *ìròyìn ẹléjẹ̀* lásán ní.
- Ìròyìn tí ó jẹ *balógun* láàárọ̀ tònìí ni pé Tinubu jáwé olúborí nínú ètò ìdìbo abẹ́lé fún àwọn òǹdíje dúpò ààrẹ lábé àsíyá ẹgbẹ́ òṣèlú APC.

Nínú àpẹẹrẹ kínní, a fún ìròyìn ní àbùdá ènìyàn "ẹ̀jẹ̀". Nínú àpẹẹrẹ kejì, balógun jẹ́ orúkọ tàbí oyè fún ènìyàn ní àwùjọ, a lo àbùdá yìí fún ìròyìn tí kì í ṣe ènìyàn

nítorí a fẹ́ jẹ́ ki àwọn olùgbọ́ mọ̀ pé ìròyìn náà ni ó ṣe pàtàkì jùlọ ní ọjọ́ náà gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe mọ̀ pé ènìyàn pàtàkì ni balógun láwùjọ.

### (ẹ) Ìfọ̀rọ̀dárà

Ìfọ̀rọ̀dárà jẹmọ́ ìlò ọ̀rọ̀ kan ní ọ̀nà àrà láti gbé ẹwà èdè jáde. O níṣe pẹ̀lu àtúnpè tàbí àtúnsọ ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n kan ní ẹ̀ẹ̀mẹ́jì tàbí ẹ̀ẹ̀mẹ́ta ní ọ̀nà òtọ̀ọ̀tọ̀ pẹ̀lú èrò láti fi bu ẹwà kún ìsọ tí a lo ọ̀rọ̀ náà nínú rẹ̀. Nínú kókó-inú-ìwé-ìròyìn, àwọn atọ́kùn máa ń ṣe àmúlò ọnà èdè nínú iṣẹ́ wọn. Iṣẹ́ pàtàkì tí wọ́n máa ń fi ọnà èdè yìí jẹ́ ni kí kókó ìròyìn dùn-ún gbọ́ tí yóò mú àwọn ènìyàn lọ́kàn láti gbọ ọ̀rọ̀ tí wọ́n fẹ́ gbé jáde. Tí wọ́n bá ti ń fi ọ̀rọ̀ kan dára, ẹwà èdè tí àwọn olùgbọ́ rí yìí yóò ko ọkàn wọn sókè tí wọn yóò sì fẹ́ gbọ́ nǹkan tí wọ́n fẹ́ sọ. A bá àpẹẹrẹ ìfọ̀rọ̀dárà yìí nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn:

Ó ń relé
Kò délé
Ó ń r'oko
Kò dóko
Ó ti oko òrókòto dóko ìrókòto
Èyí ni bí olùdárí ilé-iṣẹ́ ìjọba kan ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ ṣe kó sí ọ̀wọ́ àwọn ajínigbé nígbà tí ó ń darí bọ láti ìpàdé ní Àbújá.

'Ilé' àti 'oko' ni atọ́kùn fi dára ní ọ̀nà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ láti mú ọkàn àwọn ènìyàn tí wọ́n ń retí ọ̀rọ̀ tó fẹ́ jáde. Lẹ́yìn akitiyan ìfọ̀rọ̀dárà yìí ni atọ́kùn ṣe gbé kókó ìròyìn náà jáde fún àwọn olùgbọ́ tí wọ́n kó ọkàn ró láti mọ nǹkan tí ó ń sẹlẹ̀. A wòye pé yàtò sí pe ìfọ̀rọ̀dárà máa ń jẹ́ ki ètò mú àwọn olùgbọ́ lọ́kàn, o tún máa ń jẹ ki wọ́n nífẹ̀ẹ́ láti gbọ́ ètò náà nítorí ẹwà èdè tó mú dání.

### (f) Àmúlùmálà kóòdù

Kóòdù ni àmì tàbí èdè tí a yàn láàyò fún ìbánisọ̀rọ̀. Àmúlùmálà kóòdù ni àlòpò kóòdù nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀. A máa ń ṣe àyálò ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ nínú kóòdù mìíràn tí ó yàtọ̀ sí èyí tí a yàn fún ìbánisọ̀rọ̀ nígbà tí a bá ń safọ̀ lọ́wọ́, àlòpò àwọn kóòdù ọ̀tọ̀tọ̀ yìí ni ó jẹ́ àmúlàmálà kóòdù. Nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, àwọn atọ́kùn máa ń ṣe àmúlùmálà láti ṣe àsàyàn kókó tí wọ́n fẹ́ gbé jáde. Kóòdù tí wọ́n ba lò máa ń ní òye kan pàtàkì tí ó ń fihàn àwọn olùgbọ́. Àpẹẹrẹ:

- Ẹ má dá àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú PDP lóhùn "*Wọ́n ń "lobby"* fún ohun tí kìí ṣe tiwọn" Àsìkò wọn kò tíì tó.
- SOB sọ fún àwọn akọ̀ròyìn wí pé "*inconclusive issue"* ni àbájáde ìdìbò abélé ẹgbẹ́ òṣèlú APC tí wọ́n ṣe ni Ikorodu fún ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin ìpínlẹ̀ Èkó

Nínú àwọn àpẹẹrẹ tí a sàfihàn, a rí àlòpọ̀ kóòdù méjì; èdè Yorùbá àti èdè Gẹ̀ẹ́sì. Atọ́kùn bẹ̀rẹ̀ ìròyìn pẹ̀lú èdè Yorùbá, ó wá mú èdè Gẹ̀ẹ́sì wọnú rẹ̀, kí ó tó tún fi èdè Yorùbá tẹ̀síwájú láti parí kókó ìròyìn tí ó ń kà fún àwọn olùgbọ́. 'lobby' ní ọ̀rọ̀ tí wọ́n lò láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì láti ṣàlàyé ìhùwàsí ẹgbẹ́ òṣèlú PDP lórí ètò ìdìbò tí ó ń bọ̀ lọ́nà. Wọ́n ń sapá láti jẹ́ kí àwọn ènìyàn ṣe tiwọn. 'inconclusive issue' sàfihàn pé wọ́n kò tí yanjú ọ̀rọ̀ ìdìbò abélé náà. Ọ̀rọ̀ ṣì wà lórí rẹ̀ tí wọ́n yóò sọ kí wọ́n tó ní abájáde tí gbogbo wọn yóò tẹ́wọ́ gbà. Àtúpalẹ̀ àwọn àpẹẹrẹ yìí fihàn gbangba pé àmúlùmálà kóòdù máa ń wáyé láti ṣàlàyé kókó kan pàtàkì tó jẹ́ pé kóòdù kejì tí a lò ló lè ṣàlàyé rẹ̀ dúnjú fún àwọn ènìyàn.

## (g) Èdè àjòjì

Èdè àjòjì ni ìlò èdè mìíràn tó yàtọ̀ sí èdè tí a gbà gẹ́gẹ́ bí tiwa nínú ìsọ, ìbánisọ̀rọ̀ tàbí lítíréṣọ̀. Ní àwùjọ Yorùbá, èdè àjòjì ni Gẹ̀ẹ́sì, Lárúbáwá, Faransé, Haúsá, Jamaní abbl. Mákindé (2004:69) ṣàlàyé pé lára èròjà amédèrẹwà tí àwọn oníṣẹ́ ọ̀nà lítíréṣò máa ń lò ní èdè àjòjì. Ẹyí ni kí oníṣẹ́ ọ̀nà lítíréṣò ṣá àṣàyàn àwọn èdè àjòjì kan lò nínú iṣẹ́ rẹ̀ pẹlú èròngbà àtifa kókó kan pàtó yọ. A rí ìlò èdè àjòjì nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, tí ó sì jíṣẹ́ fífa kókó kan pàtó yọ bí Mákindé ṣe sọ. Àpẹẹrẹ:

- "*Tákùnlaì*" Ẹ jẹ́ ká bẹ̀rù ọlọ́run àti àtunbọtán nínú gbogbo tí a bá ń ṣe. Ẹgbẹ́ òṣèlú APC ló sọ bẹ́ẹ̀ fún ẹ̀gbẹ́ òṣèlú PDP lórí èrò wọn lórí ètò ọrọ̀ ajé ilẹ̀ Nàìjíríà
- Áàwù "*Ṣíkena*" ó parí fún orílé èdè Nàíjíríà tí ọ̀dọ́ bá jẹ́ ààrẹ wa lásìkò ìdàrúdàpọ̀ yìí. Ẹ̀gbẹ́ òṣèlú PDP ló sọ élèyìí di mímọ̀ fún àwọn ọmọ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà

'*Tákùnlái*' jẹ́ ọ̀rọ̀ láti inú èdè lárúbáwá tí a lè túmọ̀ sí pé kí ènìyàn bẹ̀rù ọlọ́run. Atọ́kùn ṣe àmúlò rẹ̀ láti fa kókó tí ó wà nínú ìròyìn náà pé ẹgbẹ́ òṣèlú APC ni kí ẹgbẹ́ òṣèlú PDP ṣe òtítọ́ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tí wọ́n ń sọ lórí ọrọ̀ ajé orílẹ̀ èdè Nàìjíríà kí wọ́n ma ṣe àbòsí. '*Ṣíkènà*' jẹ́ ọ̀rọ̀ láti inú èdè haúsá tí a gbà pé ó túmọ̀ sí ó parí. Kókó tí èdè àjòjì yìí ń fàyọ ni pé ó tán tàbí ìdámú dé bá Nàìjíríà tí ọ̀dọ́ bá jẹ ààrẹ lásìkó yìí nítorí ìlù náà nílò ènìyàn tí ìrírí ayé yé dáadáa gẹ́gẹ́ bí ẹgbẹ́ òṣèlú PDP se sọ ọ́.

## (gb) Àwítúnwí

Àkànmú àti Sanni (2011) ṣàlàyé pé àwítúnwí ni sísọ ọ̀rọ̀ kan lẹ́ẹ̀mejì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú ìsọ kan. Wọ́n sàfihàn pé ọ̀nà èdè yìí ṣe pàtàkì nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá, ohun sì ni òpómúléró ewì Yorùbá. Nínú èdè Yorùbá, oríṣiríṣi àwítúnwí mẹ́rin ni ó wà; àwítúnwí ẹyọ-ọ̀rọ̀, àwítúnwí alákùdé gbólóhùn, àwítúnwí odindin gbólóhùn àti àwítúnwí òye ọ̀rọ̀(Olúnládé, 2001). Àwítúnwí ẹyọ-ọ̀rọ̀ ni sísọ tàbí síṣe àpètúnpè

ọ̀rọ̀ kan ṣoṣo nínú ìsọ tàbí iṣẹ́ lítíréṣọ̀. Àwítúnwí alákùdé gbólóhùn ni àwítúnwí tó jú ẹyọ-ọ̀rọ̀ kan lọ sùgbọ́n kì í ṣe gbogbo gbólóhùn náà ni a ṣe àwítúnwí rẹ̀. Àwítúnwí odindin gbólóhùn ni àwítúnwí tí a ṣe àtúnpè gbogbo gbólóhùn tó wà nínú ìsọ kan. Àwítúnwí òye ọ̀rọ̀ ni àwítúnwí tí a ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tàbí gbólóhùn tó jẹ́ pé òye tàbí ìmọ̀ kan náà ni ó wà nínú àwọn ìsọ tí a ti ṣe àwítúnwí. Nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, a rí ìlò àwítúnwí òye ọ̀rọ̀. Àpẹẹrẹ:

Ẹni fún nilóko ni ò fẹ́ kí ebi pani
Ẹni fún niláṣọ ni kò fẹ́ ká rìn hòhò
Ẹni fún ni lọ́mọ ni kò fẹ́ kí á kú àkúrun
Tinúbú tí ran àwọn èniyàn púpò lọ́wọ́, Òun lókàn báyì. Ẹgbẹ́ òṣèlú APC ìpínlẹ̀ Èkó ló sọ bẹ́ẹ̀

*'Ẹni fún nilóko',' Ẹni fún niláṣọ'*àti *'Ẹni fún ni lọ́mọ'* jẹ́ àwítúnwí òye ọ̀rọ̀ nítorí gbogbo wọ́n ń tọ́ka sí ìrànlọ́wọ́. Ìrànlọ́wọ́ ni a fẹ́ mẹ́nubà tí a fi lo gbogbo ìsọ yìí. Lẹ́yìn tí atọ́kùn ṣe àwítúnwí yìí, ó mú ìròyìn jáde fún àwọn èniyàn láti gbọ́ àti mọ̀. Iṣẹ́ pàtàkì tí àwítúnwí yìí jẹ́ ni pé ó pe àkíyèsí àwọn èniyàn sí kókó-ọ̀rọ̀ tí wọ́n fẹ́ so, ó sì tẹpẹlẹ fún àwọn olùgbọ́. Àwitúnwí yìí yóò jẹ́ kí ọ̀rọ̀ náà máa rókì lọ́kàn gbogbo olùgbọ́.

### (h) Orin

Orin jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ọnà èdè Yorùbá. A máa ń lo orin lóríṣirísi nínú ìbánisọ̀rọ̀ àti iṣẹ́ lítíréṣọ̀. Orin a máa fún iṣẹ́ wa ni ẹwà àti adùn tó jẹ́ iṣẹ́ pàtàkì tí ọnà èdè máa ń jẹ́. Ni àárín àwọn Yorùbá, kò sí iṣẹ́ tí a kò lè fi orin ṣe. A le fi sọ̀rọ̀, kọ́nilẹ́kọ̀ọ́, kìlò, dámòràn, bániwí abbl. Ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn kò gbẹ́yìn nínú ìlo orin. Orin pàápàá ni wọ́n máa fí n bẹ̀rẹ̀ ètò náà. Orin ni wọ́n máa ń lò gẹ́gẹ́ bi ìsíde kí àwọn atọ́kùn ètò náà tó bẹ̀rẹ̀ àjọyọ tí wọ́n máa ń ṣe lórí kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Orin tí wọ́n máa ń lò nínú ètò náà ni:

Líle: Kókó inú ìwé ìròyìn,
Ìfẹ́sowápọ̀ ló gbé dé o,
Ègbè: Kókó inú ìwé ìròyìn,
Lílé: Ẹ wá nǹkan fìdílé, ẹ jẹ́ á jọ gbọ,
Ègbè: Kókó inú ìwé ìròyìn,
Lílé: Ìfẹ́sowápọ̀ tún gbé dé o,
Ègbè: Kókó inú ìwé ìròyìn,
Lílè: Níbi atọ́kùn ń pèdè tó jọjú ní gbèsè,
Ègbè: Kókó inú ìwé ìròyìn.

Iṣẹ́ pàtàkì méjì ni orin máa ń jẹ́ nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Lọ́nà kínní, ó máa ń ṣisẹ́ ìtanilólobó láti sọ fún àwọn èniyàn pé ètò náà tí fẹ́ bẹ̀rẹ̀. Lọ́nà kejì, ó máa

ń fihàn pé ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn ni a ń ṣe lọ́wọ́ nígbà tí a bá gbọ orin yìí láàrín ètò kan tí a bá wọn lẹ́nu rẹ̀.

## Pàtàkì Ìlò Ọnà Èdè Nínú Ètò Kókó-Inú-Ìwé-Ìròyìn

Àwọn ilé-iṣẹ́ rédíò kì í dédé gbé ètò kalẹ̀, ètò náà gbọ́dọ̀ ní àwọn àkóónú tó múnádóko tí ó ń ṣe àwọn olùgbọ́ ní àǹfàànì. Ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn jẹ́ ètò kan tó ń kó ipa pàtàkì láwùjọ nítorí ó máa ń mú ìròyìn dé etí ìgbọ́ àwọn ènìyàn lásìkò tó tọ́ àti tó yé. A ṣàkíyèsí pé ìlànà tí a ń gbà gbé ìròyìn kalẹ̀ lórí ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn yàtọ̀ sí bí wọ́n ṣe ń gbé ìròyìn jáde fún àwọn ènìyàn lórí àwọn ètò mìíràn lórí àwọn rédíò yóòkù. Ìlò ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn ni ó yà á sọ́tọ̀ gédegédé sí àwọn ètò tókù tí wọ́n tí ń sọ ìròyìn pọ́nbélé lórí rédíò.

Onírúurú iṣẹ́ ni ọnà èdè ń jẹ́ nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn. Ipa pàtàkì àkọ́kọ́ tí ọnà èdè ń kó nínú kókó-inú-ìwé-ìròyìn ni pé ó ń gbé àṣà àti èdè Yorùbá lárugẹ. Àfojúsùn olùdásílẹ̀ ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn ní gbígbé èdè Yorùbá láruge nípa sísọ ìròyìn pẹ̀lú èdè Yorùbá, ìlò ọnà èdè nínú ètò náà ní ó ń ṣe agbátẹrù gbígbé èdè Yorùbá láruge. Àwọn ọnà èdè yìí sàfihàn èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè tó lẹ́wà tí ó sì pé èyí tó sì ń mú kí àwọn ènìyàn nífẹ̀ẹ́ sí èdè náà. Ìlò ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn ń jẹ́ kí èdè Yorùbá máa gbèrú sí tí kò sí ní jẹ́ kí iná èdè náà jó àjórẹ̀yìn.

Ọnà èdè tún máa ń ran àwọn atọ́kùn lọ́wọ́ láti ṣiṣẹ́ wọn gẹ́gẹ́ bí akàròyìn. Wọ́n máa ń lo àwọn ọnà èdè yìí lórísìrísì láti gbé ìròyìn jáde. O máa ń sàfihàn tàbí tọ́kà kókó ìròyìn tí atọ́kùn fẹ́ gbé jáde. Ó tún máa ń jẹ́ kí àwọn kókó ìròyìn tí a kà yé àwọn olùgbọ́ nítorí a máa ń lò wọ́n láti ṣàlàyé, ṣàpèjúwe, ṣàpẹẹrẹ àti tẹpẹlẹ mọ́ kókó ìròyìn tí a lò mọ́ nígbà tí a ń sètò lọ́wọ́. Síwájú si, ọnà èdè máa tún ran àwọn atọ́kùn lọ́wọ́ láti pẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan sọ tàbí da àwọn ọ̀rọ̀ kan pè lórí ètò náà nígbà tí wọ́n ń ka kókó inú ìwé ìròyìn lọ́wọ́ kó ma bà dá wàhálà sílẹ̀ láàrín ìlú àti láti dènà orísìrísì ìjànbá tí líla irúfẹ́ ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ mọ́lè lè mú dání fún àwùjọ.

Ìlò ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn ní ó jẹ́ kí àwọn ènìyàn fẹ́ràn ètò náà tí ó sì máa ń jẹ́ ki ó mú wọn lọ́kàn nígbà tí wọ́n bá ń gbọ́ ètò yìí. Tí àwọn atọ́kùn bá ń ṣe ètò lọ́wọ́, ìlò àwọn ọ̀nà èdè lọ́nà ọ̀kan-ò-jọ̀kan máa ń jẹ́ kí ètò náà wọ àwọn olùgbọ́ lára tí wọn yóò máa fi gbogbo ẹ̀mí wọn ba lọ. Ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ káàkiri àgbáyé ni àwọn atọ́kùn ètò yóò máa ń mú lẹ́yọ kọ̀ọ̀kan tí wọn yóò sì máa fi èdè àti àlòpọ̀ ẹ̀wà èdè lórísìrísì gbe jáde sí etí ìgbọ́ àwọn olùgbọ́ wọn láì fi àkókò ṣòfò. Àwọn ọnà èdè lórísìrísì tí àwọn ènìyàn kò ma ń gbọ́ káàkiri tí wọ́n máa ń bá pàdé nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn nìkan jẹ́ kí ètò náà wùn wọn púpọ̀ tí wọ́n sì máa ń tẹ́tí si lójoojúmọ́. Nítorí náà, a lè fọwọ́ sọ̀yà pé ìlò èdè Yorùbá pàápàá jùlọ ìlò àwọn èròjà amédèdùn ìyẹn ọnà èdè ni ó jẹ́ kí ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn gbajúmọ̀ láwùjọ.

## Àléébù Ìlò Ọnà Èdè Nínú Ètò Kókó-Inú-Ìwé-Ìròyìn

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, a kì í dára títí kí a má kù sí ibì kan. Gbogbo ẹ̀dá tí Ọlọ́run dá ló ní àléébù ti rẹ̀ bí ó ti lè wù kó kéré mọ. Nítorí náà, bí ọnà èdè ṣe nípa pàtàkì tí ó ń kó nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn bẹ́ẹ̀ náà ni ó ní àwọn àléébù tí ìlò rẹ̀ ní nínú ètò náà tí ó sì ń kóbá ètò náà. Àmó, àwọn àléébù ìlò ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn kò pọ̀ tó àwọn ànfààní tí ìlò ọnà èdè ní nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn.

Àléébù àkọ́kọ́ tí ìlò ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn ní ni pé o máa ń ṣe ìdíwọ́ fún àwọn ènìyàn pàápàá jùlọ àwọn ènìyàn tí wọn kò nímọ̀ tàbí imọ̀ kíkún lórí àwọn èdè yìí láti mọ ìtumọ̀ wọn àti láti ni òye àwọn kókó ìròyìn tí a lò àwọn ọnà èdè yìí fún. Ọnà èdè jẹ́ fọ́nran pàtàkì nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, ó fẹ́rè má si kókó ìròyìn kan tí a kà láì ṣàmúlò ọnà èdè. Tí ènìyàn tàbí olùgbọ́ kan kò bá ní ímọ̀ èdè tó kún, àwọn ọnà èdè yóò jẹ́ àjòjì si nítorí náà eèyàn bẹ́ẹ̀ kò ní lè túmọ̀ àwọn ọnà èdè yìí. Bí ènìyàn tilẹ̀ ni ìmọ̀ ọnà èdè, àwọn kan wà tí wọ́n kò wọ́pọ̀ tàbí gbajúmọ̀ láàrín àwọn ènìyàn, àwọn èyí pàápàá máa ń nira fún ènìyàn láti túmọ̀ tí wọ́n bá gbọ́ wọn. Nítorí náà, ìlò ọnà èdè púpọ̀ nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn máa ń jẹ́ kí ó nira fún àwọn ènìyàn láti mọ ìtumọ̀ àti ní òye kíkún lórí àwọn kókó ọ̀rọ̀ àwùjọ tí wọ́n máa ń sọ lórí ètò náà.

Ọnà èdè tún máa ń mú ìyàtọ̀ bá ìròyìn tí a fẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ̀. Tí àwọn atọ́kùn bá lo àwọn ọnà èdè tó ní pọ́n-ọ́n-na nígbà tí wọ́n bá ń ka ìròyìn, ó máa ń mú ìyípadà bá ìtumọ̀ tàbí ǹnkan tí ó ṣẹlẹ̀ gangan tí a fẹ́ kí àwọn ènìyàn mo. Láti ara ọnà èdè lóríṣiríṣi tí wọ́n máa ń lò nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn, àwọn ènìyàn máa ń fún àwọn kókó ìròyìn ní ìtumọ̀ tí ó yàtò sí nǹkan tí ó ṣẹlẹ̀ gangan tí atọ́kùn kà sí wọn létí.

## Àgbálogbágbò

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní bí a bá gbálé tí a gbáta, ààtàn làá darí rẹ̀ sí. A ṣe àyẹ̀wò bí wọ́n ṣe ń lo àwọn ọnà èdè nínú ètò kókó-inú-ìwé-ìròyìn lórí Bond FM 92.9. A sàkíyèsí pé ọnà èdè jẹ́ fọ́nran pàtàkì tí wọ́n máa ń lò nínú ètò yìí fún àjọyọ tí wọ́n máa ń ṣe lórí ètò náà. Àwọn ọnà èdè yìí nípa pàtàkì tí wọ́n máa ń kó nínú àṣeyọrí ètò náà, kì í ṣe pé a ń lò wọ́n lásán. A ri dájú pé àwọn atọ́kùn máa ń lo àwọn ọnà èdè yìí láti jẹ́ oríṣiríṣi iṣẹ́ ni ipò ìlò wọn. Bákan náà, ìlò àwọn èròjà amédèdùn yìí tọ̀nà. Ibi tí ó yẹ ni àwọn atọ́kùn ti máa ń lo àwọn ọnà èdè yìí. Fún gbogbo ìgbà tí a fi ṣe ìwádìí lórí ètò náà, a kò pàdé ibi tí wọ́n ti lo ọnà èdè nípò tí kò yẹ. Pépà yìí sọ di mímọ̀ pé ọnà èdè ń kó ipa pàtàkì nínú ìròyìn kíkà lórí rédíò, ìgbẹ́láruge èdè Yorùbá àti àfihàn ohun tó ń lọ láwùjọ. Iṣẹ́ yìí gúnlẹ̀ pé ọnà èdè jẹ́ nǹkan pàtàkì nínú ète ìgbétò kalẹ̀ lórí rédíọ́ tí a lè lò dáadáa láti fún iṣẹ́ wa ni ẹwà kí àwọn ènìyàn lè fẹ́ràn rẹ̀ bi ti kókó-inú-ìwe-ìròyìn. Àmọ́ ṣáá, kí a yàgò fún àlòjù rẹ̀ nítorí ó máa ń mú ìsọ takoko tí ó bá ti pọjù nínú rẹ̀.

# ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adewoyin, S.Y (2010) Ìmọ̀ Èdè, Àṣà àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá fún Ile-Ẹ̀kọ́ Sẹ́kọ́ńdírí Àgbà S.S.3. Lagos: Corpromutt Publishers.
Akanmu, S.O àti Sanni, R.A (2011) Ìlò èdè Yorùbá. Lagos: Joytal Printing Press.
Kehinde, T. (2001) Ìlò èdè Yorùbá. Lagos: Olomu Books.
Makinde, S.O. (2000) Ìlò èdè Yorùbá fún olùkọ́ àti akékọ̀ọ́. Lagos: Babs Olatunji Press & Books Production.
Olunlade, T. A (2001) Ìlò èdè. Lagos: Fola Printing Press and Publishing Company Limited.

## Ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò

Abẹ́nà ìmọ̀ – Ọ̀gbẹni Túnji Olálékan
Ọjọ́ ìṣèwádìí – Ọjọ́ kejìlélógun, Osù kárùn-ún 2022.
Ibi ìṣèwádìí – BOND FM 92.9, Ikeja, Lagos State.